# IDAJỌ AWỌN ORILẸ-ÈDE

## Isaiah 11:10-16; Matteu 25:31-46; Luku 19:11-27; 22:28-30; Filippi 2:9-11; Ifihan 20:1-6

### ẸKỌ 167 --- FUN AGBA ATI ỌDỌ

**AKỌSORI: "Lõtọ ni mo wi fun nyin, niwọn bi ẹnyin ti ṣe e fun ọkan ninu awọn arakọnrin mi wọnyi ti o kere julọ ẹnyin ti ṣe e fun mi" (Matteu 25:40).**

**"Nigbati Ọmọ-enia yio wá ninu ogo rẹ̀, ati gbogbo awọn angẹli mimọ́ pẹlu rẹ̀, nigbana ni yio joko lori ìtẹ́ ogo rẹ̀:**

**"Niwaju rẹ̀ li a o si kó gbogbo orilẹ-ède jọ: yio si yà wọn si ọ̀tọ kuro ninu ara wọn, gẹgẹ bi oluṣọ-agutan ti iyà agutan rẹ̀ kuro ninu ewurẹ:**

**"On o si fi agutan si ọwọ́ ọtún rẹ̀, ṣugbọn awọn ewurẹ si ọwọ́ osi.**

**"Nigbana li Ọba yio wi fun awọn ti o wà li ọwọ́ ọtun rẹ̀ pe, Ẹ wá, ẹnyin alabukun-fun Baba mi, ẹ jogún ijọba, ti a ti pese silẹ fun nyin lati ọjọ ìwa:**

**"Nitori ebi pa mi, ẹnyin si fun mi li onjẹ: ongbẹ gbẹ mi, ẹnyin si fun mi li ohun mimu: mo jẹ alejò, ẹnyin si gbà mi si ile:**

**"Mo wà ni ihoho, ẹnyin si daṣọ bò mi: mo ṣe aisan, ẹnyin si bojuto mi: mo wà ninu tubu, ẹnyin si tọ̀ mi wá.**

**"Nigbana ni awọn olõtọ yio da a lohun wipe, Oluwa, nigbawo li awa ri ti ebi npa ọ, ti awa fun ọ li onjẹ? Tabi ti ongbẹ, ngbẹ ọ, ti awa fun ọ li ohun mimu?**

**"Nigbawo li awa ri ọ li alejò, ti a gbà ọ si ile? Tabi ti iwọ wà ni ihoho, ti awa daṣọ bò ọ?**

**"Tabi nigbawo li awa ri ti iwọ ṣe aisan, ti a bojuto ọ? Tabi ti iwọ wà ninu tubu, ti awa si tọ̀ ọ wá?**

**"Ọba yio si dahùn yio si wi fun wọn pe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, niwọn bi ẹnyin ti ṣe e fun ọkan ninu awọn arakọnrin mi wọnyi ti o kere julọ ẹnyin ti ṣe e fun mi.**

**"Nigbana ni yio si wi fun awọn ti ọwọ́ òsi pe, Ẹ lọ kuro lọdọ mi, ẹnyin ẹni egun, sinu iná ainipẹkun, ti a ti pèse silẹ fun Eṣu ati fun awọn angẹli rẹ̀:**

**"Nitori ebi pa mi, ẹnyin kò si fun mi li onjẹ: ongbẹ gbẹ mi, ẹnyin kò si fun mi li ohun mimu:**

**"Mo jẹ alejò, ẹnyin kò gbà mi si ile: mo wà ni ihoho, ẹnyin kò si daṣọ bò mi: Mo ṣàisan, mo si wà ninu tubu, ẹnyin kò bojuto mi.**

**"Nigbana ni awọn pẹlu yio dahùn wipe, Oluwa, nigbawo li awa ri ti ebi npa ọ, tabi ti ongbẹ ọ, tabi ti iwọ jẹ alejò, tabi ti iwọ wà ni ihoho, tabi ninu aisan, tabi ninu tubu, ti awa kò si ṣe iranṣẹ fun ọ?**

**"Nigbana ni yio da wọn lohun wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, niwọn bi ẹnyin kò ti ṣe e fun ọkan ninu awọn ti o kere julọ wọnyi, ẹnyin kò ṣe e fun mi.**

**"Awọn wọnyi ni yio si kọja lọ sinu iya ainipẹkun: ṣugbọn awọn olõtọ si iye ainipẹkun" (Matteu 25:31-46).**

Lẹhin ti ifarahàn Kristi ba ti kọja tan ti a si jagun Armageddoni ti a si bori awọn ti o dide si Kristi ati awọn ẹgbẹ ọmọ-ogun ti Ọrun, ohun ti yoo wa tẹle awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ wọnyi ninu eto nla Ọlọrun lati ayebaye, ni gbigbé Ijọba Kristi kalẹ ninu aye. Ijọba yii ni a n pe ni Ijọba Ẹgbẹrun (1,000) ọdun tabi Igba Alaafia. Yoo wà fun ẹgbẹrun ọdún, yoo si jẹ akoko ayọ̀ pupọ, paapaa ju lọ fun awọn ẹni irapada, nitori egun kò ni si mọ́, a o si gbé Satani dè. Oun kò ni le tan awọn orilẹ-ède jẹ mọ́ titi opin ẹgbẹrun ọdun. Yoo jẹ akoko ti a o fi ododo ṣe idajọ. Kristi ni i ṣe Adajọ Agba, awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ aṣẹgun ni a si le pe ni "adajọ kékèké." Idajọ yii ni a n pe ni Idajọ awọn Orilẹ-ède.

## Awọn Idajọ ninu Eto Ọlọrun

Kò si ọ̀rọ "Idajọ gbogbo-gbò" ninu Iwe Mimọ́. Bi awọn miran ti ṣe n lo o ti dá ariyanjiyan pupọ silẹ, eyi si ti yọri si oriṣiriṣi ero ati awọn ẹkọ ti o lodi si Bibeli. Ṣugbọn ọ̀na kan wà lati lo ọ̀rọ naa ni ọ̀na ti o tọ̀na. Idajọ Ọlọrun wà fun gbogbo eniyan lọna bayii pe, gbogbo eniyan ni a o ṣe idajọ rẹ̀ (Romu 14:10; II Kọrinti 5:10), ṣugbọn kò tumọ si wi pe gbogbo eniyan ni a o ṣe idajọ fun nigbà kan naa.

Kò tilẹ mu ọgbọn wa rara lati sọ pe awọn eniyan mimọ́ ti a gbà soke lọ si ibi Ase-alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, ati awọn eniyan mimọ́ ti akoko Ipọnju Nla ti a ji dide nigba Ifarahàn Kristi, ninu ara ologo ti wọn si joko pẹlu Kristi lori aga idajọ, yoo tun duro pẹlu awọn ẹni irira, awọn apaniyan, awọn abanijẹ, awọn ọ̀muti, awọn eleke, ati

awọn oluṣe buburu lati gba idajọ. A kò ni dá awọn eniyan mimọ́ ti wọn ti ji dide ni Ajinde Kinni lẹjọ ni ibi Itẹ́ Idajọ Nla Funfun. Awọn ẹlomira n kọ́ pẹlu atilẹhin awọn ẹsẹ Iwe-Mimọ́ ti a le fara mọ, wi pe kaka bẹẹ, awọn eniyan mimọ́ wọnyi, yoo joko lori aga idajọ pẹlu Kristi nibi Itẹ́ Idajọ Nla Funfun, lati ṣe idajọ awọn ẹlẹṣẹ ti yoo fara hàn nibẹ. Nitori naa a le ri i wi pe awọn Onigbagbọ́ ti a ti ji dide tabi ti a ti pa lara dà ti wọn si ba Kristi joko lori itẹ́ ati aga idajọ ati aṣẹ, ni a ti ṣe idajọ wọn ṣiwaju akoko ti Itẹ́ Idajọ Nla Funfun.

Awọn Onigbagbọ́, gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ ni a ti ṣe idajọ wọn ninu Kristi. Nigbà ti Kristi kú, O gba iya ẹ̀ṣẹ ẹni kọọkan jẹ tikara Rẹ. Nigbà ti a ba fi Ẹjẹ Rẹ wẹ ọkàn kan, ti a si wẹ ẹ̀ṣẹ rẹ nù kuro, ẹni naa kò si labẹ idajọ mọ́ (I Timoteu 5: 24). Kristi ti kó ẹ̀ṣẹ rẹ lọ. A ti ṣe ètutu fun ẹ̀ṣẹ wọnyi nipa ikú Kristi niwọn igbà ti Kristi ti gba iyà gbogbo wa jẹ. Niwọn igba ti ẹni ti o ṣẹ̀ṣẹ̀ di atunbi yii ba wà ninu Ẹ̀jẹ Jesu, ti kò si pada sinu ẹ̀ṣẹ mọ́, o bọ́ lọwọ ẹbi tabi idajọ (Romu 8:1). (Ka Johannu 5:24; 3:17-19 pẹlu, ki o si ranti pe, itumọ awọn ọrọ wọnyi: **dalẹbi** ati **ẹbi** ninu Iwe Mimọ́ ja si **dalẹjọ** tabi **idajọ**).

**"Nigbati nwọn si ngbọ́ nkan wọnyi, o fi ọ̀rọ kún u, o si pa owe kan, nitoriti o sunmọ Jerusalẹmu, ati nitoriti nwọn nrò pe, ijọba Ọlọrun yio farahàn nisisiyi.**

**"O si wipe, Ọkọnrin ọlọlá kan rè ilu òkere lọ igbà ijọba fun ara rẹ, ki o si pada.**

**"O si pè awọn ọmọ-ọdọ rẹ mẹwa, o fi mina mẹwa fun wọn, o si wi fun wọn pe, Ẹ mã ṣowo titi emi o fi de.**

**"Ṣugbọn awọn ọlọ̀tọ ilu rẹ korira rẹ, nwọn si rán ikọ̀ tẹ̀le e, wipe, Awa kò fẹ ki ọkọnrin yi jọba lori wa.**

**"O si ṣe, nigbati o gbà ijọba tan, ti o pada de, o paṣẹ pe, ki a pè awọn ọmọ-ọdọ wọnni wá sọ́dọ rẹ, ti on ti fi owo fun nitori ki o le mọ̀ iye ere ti olukuluku fi iṣowo jẹ.**

**"Eyi ekini wá, o wipe, Oluwa, mina rẹ jère mina mẹwa si i.**

**"O si wi fun u pe, O ṣeun, iwọ ọmọ-ọdo rere: nitoriti iwọ ṣe olõtọ li ohun kikini, gbà aṣẹ lori ilu mẹwa.**

**"Eyi ekeji si wá, o wipe Oluwa, mina rẹ jère mina marun.**

**"O si wi fun u pẹlu pe, iwọ joye ilu marun.**

**"Omiran si wá, o wipe Oluwa, wò mina rẹ ti mbẹ li ọwọ́ mi ti mo di sinu gèle:**

**"Nitori mo bẹ̀ru rẹ, ati nitoriti iwọ ṣe onrorò enia: iwọ a ma mu eyi ti iwọ kò fi lelẹ, iwọ a si ma ká eyi ti iwọ kò gbin.**

**"O si wi fun u pe, Li ẹnu ara rẹ li emi o ṣe idajọ rẹ, iwọ ọmọ-ọdọ buburu. Iwọ mọ̀ pe onrorò enia ni mi, pe emi a mã mu eyi ti emi ko fi lelẹ, emi a si mã ká eyi ti emi kò gbin.**

**"Ẽha si ti ṣe ti iwọ kò fi owo mi si ile elé, nigbati mo ba de, emi iba si bère rẹ ti on ti elé?**

**"O si wi fun awọn ti o duro leti ibẹ̀ pe, Ẹ gbà mina na lọwọ rẹ, ki ẹ si fii fun ẹniti o ni mina mẹwa.**

**"Nwọn si wi fun u pe, Oluwa, o ni mina mẹwa.**

**"Mo wi fun nyin pe, Ẹnikẹni ti o ni, li a o fifun; ati lọdọ ẹniti kò ni, eyi na ti o ni li a o gbà lọwọ rẹ.**

**"Ṣugbọn awọn ọtá mi wọnni, ti kò fẹ ki emi ki o jọba lori wọn, ẹ mu wọn wá ihinyi, ki ẹ si pa wọn niwaju mi" (Luku 19:11-27).**

A o ṣe idajọ awọn eniyan mimọ́ gẹgẹ bi iṣẹ wọn. Eyi le má jẹ lori ilẹ ayé. O ṣe e ṣe ki eyi jẹ ọkan ninu awọn ohun pataki ti a o ṣe ni akoko Ase-alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, nitori pe awọn eniyan mimọ́ yoo ba Kristi pada bọ̀ gẹgẹ bi oloye. O dabi ẹni pe Iwe Mimọ́ fi idi rẹ mulẹ pe a o ti fun wọn ni aṣẹ. A o fun wọn ni ipo ọlá ni Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun ti Kristi (I Tẹssalonika 4:13-18; II Tẹssalonika 1:6-10; Ifihan 5:9, 10; 19:11-16). Idajọ fun ẹ̀ṣẹ ti a ti fi ji awọn eniyan mimọ́ wọnyi ti kọja. Gẹgẹ bi a ti ri i, a ti ṣe idajọ yii ni Kalfari (Heberu 9:28). Pipin ere fun awọn eniyan mimọ́ fun iṣe ati iṣẹ ododo wọn ni yoo ṣẹlẹ niwaju "itẹ-idajọ Kristi", eyi ti a mọ pe yoo waye ni igba Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan.

Awọn eniyan orilẹ ati ède ti wọn wà laye ni akoko Ifarahàn, awọn ti a kò fi didan ogo Rẹ parun nigba ti Kristi pada wá, gẹgẹ bi awọn ti o dojuja kọ Ọ, ni a o da lẹjọ ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun ọdun, nigba ti gọngọ idajọ yoo ma sọ leralera lori awọn orilẹ-ède ti ki i ṣe Onigbagbọ́ ti wọn wa láyé nigba naa (Ifihan 2:27; 19:15). Kristi ni Onidajọ alaaye ati oku (Iṣe Awọn Apọsteli 10:42; II Timoteu 4:1; I Peteru 1:3-5). Ijọ Ọlọrun tabi awọn eniyan mimọ́ aṣẹgun ti a ti gbà soke ni akoko Ipalarada, yoo ba Kristi pada wá lati ṣe idajọ aye tabi awọn orilẹ-ède ti o wa laye (I Kọrinti 6:2; Juda 14:15; Matteu 13:40-43). Eyi ni idajọ awọn alaaye ti n bẹ lori ilẹ aye. Awọn Apọsteli yoo joko lori itẹ́ lati ṣe idajọ awọn ẹya Israẹli mejila.

**"Ẹnyin li awọn ti o ti duro ti mi ninu idanwo mi.**

**"Mo si yàn ijọba fun nyin, gẹgẹ bi Baba mi ti yàn fun mi;**

**“Ki ẹnyin ki o le mã jẹ, ki ẹnyin ki o si le mã mu lori tabili mi ni ijọba mi, ki ẹnyin ki o le joko lori itẹ́, ati ki ẹnyin ki o le ma ṣe idajọ fun awọn ẹ̀ya Israẹli mejila” (Luku 22:28-30).**

Awọn ti a pa ninu ogun Armageddoni, ati awọn ti o tun kú lẹhin eyi lai ni igbala yoo duro niwaju Itẹ Idajọ Funfun pẹlu awọn eyi ti o kù, awọn okú ati alaaye ti wọn ti wà lati ayebaye, ti a kò ti i dá lẹjọ ṣiwaju idajọ yoo kadi gbogbo idajọ. Ṣugbọn idajọ awọn Orilẹ-ède yatọ si ti Itẹ Idajọ Nla Funfun nitori pe ki yoo dẹkun ni gbogbo akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun; dajudaju ki i ṣe ẹyọ idajọ igbà kanṣoṣo pere bi ti Itẹ Idajọ Nla Funfun.

**Idọgba Ọ̀na Idajọ Ọlọrun ati ti Eniyan**

Ninu akoso orilẹ-ède wa, a ni oriṣiriṣi ile-ẹjọ ti wọn n ṣe abojuto oriṣiriṣi ati oniruuru ẹjọ ati ọ̀ràn didá. Eniyan kan le fara hàǹ ni ile-ẹjọ fun idi pupọ. O le lọ lati mọ̀ bi ofin kan fẹsẹ mulẹ tabi bẹẹ kọ, lati mọ ohun ti i ṣe ojuṣe rẹ̀ labẹ ofin, tabi lati mọ bi ofin kan ti fẹsẹ mulẹ to fun anfaani awọn ẹlomiran. A le mu un wa si ile-ẹjọ lati wa jẹjọ awọn ẹ̀sun ti a fi i sun fun, bi o ba ti ṣe aṣiṣe lọna kan tabi bi o ba ti da ọran kan. Ni oniruuru igbekalẹ ile-ẹjọ wọnyi, a le fi i sinu tubu, tabi ki o san owo itánràn, ki a jẹ ẹ niya, tabi ki a fun un ni imọran, tabi ki a da a lare gẹgẹ bi ẹ̀sun ti a fi i sun fun, tabi bi ọ̀ran ti o dá ti a fi gbè e wa sile ẹjọ ba ti ri.

Awọn ile-ẹjọ miiran si wà ti o ni agbara ikú ati iye lori awọn ti a ba mu wá siwaju wọn ti a si sùn ni ẹ̀sun lile. Awọn ile-ẹjọ wọnyi le paṣẹ ti yoo gba ominira tabi ẹmi ọdaran naa paapaa bi o ba tọ bẹẹ loju wọn. Nigba ti a ba si mu iru idajọ bayii ṣẹ a fi òté le ọ̀rọ̀ naa niwọn igba ti a ti gbà ẹmi arufin, orilẹ-èdè a si bọ lọwọ ewu ati ibalo ẹni ti kò naani ẹtọ awọn ẹlomiran, ti o si gba ẹmi ẹlomiran lai nidii.

Bakan naa ni o ri pẹlu eto idajọ Ọlọrun, ṣugbọn lọna ti o yanju ju lọ. Idajọ wà fun awọn Onigbagbọ́ ninu eyi ti a o fun ni ni iyin, ti a o si pin èrè, ti a o si fun awọn eniyan mímọ́ ni aṣẹ gẹgẹ bi iṣẹ ati isin wọn ni aye ba ti ri (II Timoteu 4:8). Ṣugbọn idajọ si tun wà nibi ti a o gbe jẹ awọn eniyan niya.

Eniyan a maa jiya fun ẹ̀ṣẹ́ rẹ láyé ni iwọnba. Idajọ ninu aanu ni eyi, ni igbesi aye ẹni kọọkan wa. Ọlọrun a maa ba wa wi bi a ba ṣe aṣiṣe, lati fi ìkùnà ti o wà ni ọna wa hàn wa, ki O le mu wa pada sọdọ ara Rẹ̀ lọna bayii. Oun a maa fi okùn ifẹ fa wa, eyi ti o le jẹ fifi ọwọ́ ibawi lé wa lara lati mu wa pada si ironupiwada nigbà ti a ba ṣe agidi. Aanu wà ninu irú awọn idajọ bawọnyi.

Ṣugbọn irú idajọ wọnyi kò mu idajọ ti ikẹyin ti o n bọ̀ wa kuro (Heberu 9:27). Ọlọrun ni ẹtọ lati mu olukuluku eniyan wa si idajọ fun ẹ̀ṣẹ̀ ti ẹni naa kò ronupiwada rẹ̀, ki a si dariji i. Eyi yoo ṣẹlẹ ni opin Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun, eyi naa ni a si n pe ni Itẹ Idajọ Nla Funfun, eyi ti a ti mẹnu kàn ninu ẹkọ yii tẹlẹ. A fi otitọ yii ye ni nibi pupọ ninu Iwe Mimọ́. Lẹhin igbà ti Kristi ba fara hàn, ati ṣiwaju Itẹ Idajọ Nla Funfun ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun, a o ṣe idajọ awọn orilẹ-ède ti o wà laaye. Idajọ yii fara jọ ọpọlọpọ idajọ ati eto akoso ilu ti igbesi aye wa lọjọọjọ.

**Idajọ awọn Orilẹ-ède ti O Wà Laaye**

**“Mo si ri angẹli kan nti ọrun sọkalẹ wá, ti on ti iṣika ọgbun ni, ati ẹ̀wọn nla kan li ọwọ rẹ̀.**

**“O si di dragoni na mu, ejò atijọ ni, ti iṣe Èṣu, ati Satani, o si dè e li ẹgbẹrun ọdún.**

**“O si gbè e sọ sinu ọgbun na, o si ti i, o si fi èdidi di i lori rẹ̀, ki o má bã tan awọn orilẹ-ede jẹ mọ́ titi ẹgbẹrun ọdún na yio fi pé: lẹhin eyi, a kò le ṣai tu u silẹ fun igba diẹ.**

**“Mo si ri awọn itẹ́, nwọn si joko lori wọn, a si fi idajọ fun wọn: mo si ri ọkàn awọn ti a ti bẹ́ lori nitori ẹri Jesu, ati nitori ọ̀rọ Ọlọrun, ati awọn ti kò si foribalẹ fun ẹranko na, ati fun aworan rẹ̀, tabi ti kò si gbà àmi rẹ̀ ni iwaju wọn ati li ọwọ́ wọn: nwọn si wà lãye, nwọn si jọba pẹlu Kristi li ẹgbẹrun ọdún.**

**“Awọn okú iyokù kò wà lãye titi ẹgbẹrun ọdún na yio fi pé. Eyi li ajinde ekini.**

**“Olubukun ati mimọ́ ni ẹniti o ni ipa ninu ajinde ekini na: lori awọn wọnyi ikú ekeji kò li agbara, ṣugbọn nwọn o jẹ alufa Ọlọrun ati ti Kristi, nwọn o si mã jọba pẹlu rẹ̀ li ẹgbẹ̀run ọdún” (Ifihan 20:1-6).**

Ẹwà awọn ohun ti Ọlọrun kọ̀kọ̀ da si ayé yii ti o wọmi nigbà ti eniyan ṣubu, ki yoo fara hàn mọ titi “ifihan awọn ọmọ Ọlọrun” – ajinde awọn eniyan mimọ́ ni ara ologo. A o mu ègún ẹṣẹ kuro ninu aye, gbogbo aye yoo si di Paradise.

A o de Satani a o si sọ ọ si ọgbun ainisalẹ fun ẹgbẹrun ọdún, ki yoo si le danwo tabi tan awọn eniyan ti o wà ni aye jẹ ni gbogbo akoko naa (Ifihan 20:1-3). Kristi yoo fi ọ̀pá irin ṣe akoso awọn orilẹ-ède: ṣugbọn yoo jẹ Ijọba ododo ati àìṣègbè (Iṣe Awọn Apọsteli 17:31; Ifihan 19:15). Ṣugbọn bi awọn eniyan ba mọọmọ yan ni idanu ara wọn lati ṣọtẹ, a o dá wọn lẹjọ, a o si jẹ wọn níyà (Isaiah 28:17). Irú agbara bayii ni awọn adajọ ile-ẹjọ orilẹ-èdè wa ni, bakan naa ni yoo ri ni Igba Alaafia, nitori pe Kristi ni yoo jẹ Olu Ijọba ti o wà labẹ akoso Ọlọrun nigba naa.

Fun igba kin-in-ni lẹyin ti eniyan ti ṣubu, eniyan yoo wà ninu aye lai si idanwo Eṣu, ti n gbokegbodo nisinsinyi, ti o n bu ramuramu bi kinniun, "ti o n wa ẹniti yio pa jẹ kiri" (I Peteru 5:8). Kò ni si aiṣododo mọ, nitori pe Ijọba Kristi yoo jẹ ti otitọ ati ododo (Jeremiah 23:5,6). Awọn ọ̀lọ́rọ̀ ti o ni ọkẹ aimoye naira, ki yoo jẹ gaba lori awọn talaka mọ, nitori lati Jerusalẹmu ni idajọ otitọ yoo maa jade lọ (Mika 4:1-4). Awọn eniyan yo gbe ni alaafia ati ailewu (Esekiẹli 34:25). Akoko yii yoo jẹ akoko idajọ, ati igbọran si Onidajọ aayè ati okú (Romu 14:10).

**"Ati li ọjọ na, (ọjọ Oluwa), kukute Jesse kan yio wà, ti yio duro fun ọpágun awọn enia; on li awọn keferi yio wá ri: isimi rẹ̀ yio si li ogo.**

**"Yio si ṣe li ọjọ na, ni Oluwa yio tun nawọ rẹ̀ lati gbà awọn enia rẹ̀ iyokù padà, ti yio kù, lati Assiria, ati lati Egipti, ati lati Patrosi, ati lati Kuṣi, ati lati Elamu, ati lati Ṣinari, ati lati Hamati, ati lati awọn erekùṣu okun wá.**

**"On o si gbe ọpagun kan duro fun awọn orilẹ-ède, yio si gbá awọn àṣati Israẹli jọ, yio si kó awọn ti a tuka ni Juda jọ lati igun mẹrin aiye wá.**

**"Ilara Efraimu yio si tan kuro; a o si ke awọn ọta Juda kuro; Efriamu ki yio ṣe ilara Juda, Juda ki yio si bà Efriamu ninu jẹ.**

**"Ṣugbọn nwọn o si fò mọ ejika awọn Filistini siha iwọ̀-õrun; nwọn o jùmọ bà awọn ti ila-õrun jẹ: Nwọn o si gbe ọwọ́ le Edomu ati Moabu; awọn ọmọ Ammoni yio si gbà wọn gbọ́.**

**"OLUWA yio si pa ahọn okun Egipti run tũtũ; ẹfũfu lile rẹ̀ ni yio si mi ọwọ́ rẹ̀ lori odo na, yio si lù u ni iṣàn meje, yio si jẹ ki enia rekọja ni batà gbigbẹ.**

**"Ọna opopo kan yio si wà fun iyokù awọn enia rẹ̀, ti yio kù, lati Assiria; gẹgẹ bi o ti ri fun Israẹli li ọjọ ti o goke jade kuro ni ilẹ Egipti" (Isaiah 11:10-16).**

O rọrun lati ri aworan ọna iyanu Ọlọrun ti o gún ti o si tọ́ bi o ba tilẹ jẹ wi pe oju aanu, ifẹ, ati ododo wa bi eniyan ni a fi wo inu Ọrọ Mimọ́ Rẹ̀. Bi "OLUWA (ba) lọra lati binu, (ti) o si tobi li agbara, ni didasilẹ̀ (ti) ki yoo dá enia buburu silẹ", bi O ba "ni ọ̀na rẹ̀ ninu ãjà ati ninu iji, (ti) awọsanma si jẹ ekuru ẹsẹ rẹ̀" (Nahumu 1:3), nigbà naa o yẹ ki o dá wa loju pe ni ẹgbẹrun ọdún ti a o fi de Satani, ti Kristi yoo si jọba ninu aye yii, Oun yoo jọba gẹgẹ bi ọna otitọ ati ododo Rẹ̀. Kò ni si abẹtẹlẹ, yiyi idajọ po, yiyi akọsilẹ ile-ẹjọ po, piparun ẹri ti o le fi otitọ hàn, yiyi ẹjọ po, aṣiṣe ninu iwadii ati iṣakoso, ati awọn ohun miiran bẹẹ bẹẹ nipasẹ eyi ti awọn ọmọ-eniyan n jiya lọjọ oni.

**"Nitorina Ọlọrun pẹlu si ti gbé e ga gidigidi, (Jesu), o si ti fi orukọ kan fun u ti o bori gbogbo orukọ:**

**"Pe, li orukọ Jesu ni ki gbogbo ẽkun ki o mã kunlẹ, awọn ẹniti mbẹ li ọrun, ati awọn ẹniti mbẹ ni ilẹ, ati awọn ẹniti mbẹ nisalẹ ilẹ;**

**"Ati pe ki gbogbo ahọn ki o mã jẹwọ pe, Jesu Kristi ni Oluwa, fun ogo Ọlọrun Baba" (Filippi 2:9-11).**

Gbogbo aṣẹ yoo wà lọwọ Kristi, Onidajọ ododo (Sekariah 14:9). Oun yoo mọ aṣiri gbogbo eniyan (Romu 2:16). Oun yoo ṣe idajọ ododo (Iṣe Awọn Apọsteli 17:31). Oun ni yoo ṣe akoso idajọ gbogbo (Isaiah 45:23; Johannu 5:22; Romu 14:10-12; Filippi 2:10). Oun yoo fun awọn olododo ni ère (Orin Dafidi 58:11). Gbogbo eniyan ni yoo ni anfaani lati ni imọ pipé nipa ofin ti a fi n ṣe idajọ wọn, nitori pe Ọrọ Ọlọrun ni ofin naa (Orin Dafidi 96:13; Isaiah 2:2-4; Sekariah 14:16-19). (Ni akoko Ase Agọ ni awọn Ọmọ Israẹli maa n ni anfaani pataki lati kọ́ Ofin Ọlọrun).

Akoko ti a le maa foju sọna fun pẹlu ayọ̀ ni yii ti ki i si ṣe pẹlu abamọ. Akoko yii ni gbogbo ẹda n kerora fun, ti ọkán gbogbo eniyan si n ṣafẹri, bi o tilẹ jẹ pe wọn kò mọ okodoro nnkan ti wọn n lepa, ti wọn n ṣaapọn fun, ti wọn si n ṣiṣẹ fun (Romu 8:18-23). Akoko ologo ni yoo jẹ fun awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun ti wọn ti jinde (Isaiah 35:1-10; 65:25). Wọn yoo ni ara titun – ara ologo. Ara atijọ ti o mọ aisan, irora, ijatilẹ, ati ailera kò ni si mọ́. Wọn yoo dabi Ọba wọn, nitori nigba naa ni a o ri Oluwa ati Olugbala ni ojukoju, a o si mọ̀, gẹgẹ bi awa pẹlu si ti di mimọ (I Kọrinti 13:9-12; I Johannu 3:2, 3; Romu 18:18-23).